

# IRETI WA Funmi

# IRETI WA
# Funmi

Omo re kansoso pada wa si ile nitori won lee kuro ni ile iwe pe ko i ti i san owo ile iwe re. Ni osu meji seyin, oun je okan ninu awon igba osise ti won da duro lenu ise ni ibi ti o ti nsise. Losu tokoja na ni ijoba wo ibi ti iyawo re ti n ta oja lule nitori ibe ni oju ona titun ti won sese nse yoo gba koja.

Gbogbo isele ibanuje yi domi tutu si okan Bensini, o si gba wipe kosi ona abayo fun oun mo. Okan re poruru bi o ti dubule si ori ibusun re. Bensini wa oko re de ori afara odo nla kan pelu ero lati gba emi ara re ki itan ibanuje aye re si pari sibe

*Ki o si kepe mi ni ojo iponju: emi yoo gba o, iwo yoo si ma yin mi logo,*
**Orin Dafidi 50:15.**

Bensini! Bensini! Bensini! kilode ti o fe pa ara re? Jesu ti ku fun o, o lo si ori igi

agbelebu nitori ki ojo ola re le dara, ki o si le ni ireti. Won lu u, won pa a lara, won gbe ko si ori igi agbelebu nitori ki iwo ma ba a ni iriri inira ati osi.

Bensini wipe, "ohun ti e so yi ko yemi rara, ohun ti mo nla koja bayi kise oro nipa  inira ati osi nikan, oju timi, mo se opolopo eleya. Emi o ri owo ile iwe omo mi san, iyawo mi ti n rimifin diedie. Ngbati mo tile si nsise paapa, mi o ri owo ra oogun ti mo n lo fun eje riru, kama se wa so ti isinyi ti n ko nise lowo mo! Woo, je ki n gbemi ara mi jare", pelu omije loju ni o fi n so oro yi.

Esu ni o n se okunfa gbogbo inira ati osi ti o wa laye gegebi Bibeli ti so ni Johanu 10:10-11

*Ole ki i wa bikose lati jale, ati lati pa, ati lati parun; emi wa ki won le ni iye, ani ki won le ni i lopolopo. Emi ni oluso agutan rere; oluso agutan rere fi emi re lele nitori awon agutan.*

Jesu ti san owo itanran nitori re ki iwo ba leni ohun gbogbo ti aye re kolese alaini, ati iwa-bi Olorun.

*Bi agbara re bi Olorun ti fun wa ni ohun*

*gbogbo ti i se ti iye ati ti iwa-bi-Olorun, nipa imo eniti o pe wa nipa ogo ati olanla re.*
**2 Peteru 1:3.**

Esu fe ki o pa ara re ki oun le se ajoyo le o lori nigbati iwo ba laju si orun apadi. Bi o ba ti de si orun apadi, iwo koni le pada mo, koni si anfani ironupiwada mo, ayafi abamo nitori kosi ona abayo mo. Looto looto ni orun apadi wa, bi o ti wu ki Esu mu ki o dabi wipe ibe rorun to. Esu n se eleyi lati si eniyan lona ki won mase ronu nipa ewu ti o wa ninu lilo si orun apadi. Orun apadi je ibi inira, ijiya ti ko lopin ati ina ti ki-i-ku.

Bensini, jowo mase pa ara re ki o ma ba lo sorun apadi. Mase fun Esu ni anfani lati fi aye ati ayanmo re sofo danu; Mase je ki o so iyawo re di opo, ki omo re ti o feran mase di omo alaini baba! Iwo yoo kabamo bi o ba gba Esu laaye ki eyi ki o sele.



Woo Bensini!, Nje iwo mo eyi? kise wipe Jesu ku fun o nikan, o tun jinde ni ojo keta, ki o ba le rorun fun o lati gbe igbe aye rere ni aye yi. Igbesi aye ti Esu koni agbara ati ase lori re. Jesu wa laaye looto looto, Oun ni Olodumare, nitorina o ni

agbara lati gba o kuro ninu gbogbo iponju re wonyi.

*E wa sodo mi gbogbo eyin ti nsise, ti a si di eru wiwo le lori, emi oyoo si fi isimi fun yin.*
**Matiu 11:28**

Nje o le ranti obirin yen ni Luku 8:43-44?



*...obirin kan ti o ti ni isun eje lati igba odun mejila, ti o ti na ohun gbogbo ti o ni fun awon onisegun, beni a ko le mu u larada lati owo enikan wa, O wa si eyin re, o fi owo kan iseti aso re; logan ni isun eje re si gbe.*
**Luku 8:43-44**

O sawa si odo Jesu, o si ri iwosan pipe. Odun mejila inira, ijiya ati itiju dopin nipa ifowokan igbagbo.

Bensini; Wa sodo Jesu, Oun yoo fopin si gbogbo ijakule aye re.

Wa sodo re tokantokan, ki o si fi igbagbo yonda idari ati isakoso aye re fun u.



Bi o ko ba yonda aye re fun u, Esu yoo joba lori aye re.

Pelu edun okan ni Bensini beere wipe, 'bawo ni mo se le yonda aye mi fun Jesu? 'Gbadura ijewo ese yi:

*Jesu Oluwa, mo yan lati gba ise re fun ominira loni yi. Mo wa sodo re tokantokan mi, gba mi bi omo re, wemimo kuro ninu gbogbo ese mi ti won ti fi mi sinu ide Esu, gba mi loniyi ki o je Oluwa ati Olugbala mi. Mo yonda okan mi fun o. Fun mi lagbara ki nledi omo re. Mo dupe lowo re Jesu wipe o gbami, ti o si di Oluwa ati Olugbala mi loni yi.*



Oogun bo Bensini bi o ti taji kuro ninu orun asunwora ti o sun. O wa ye e wipe ala ni oun nla, o si mo wipe nse ni Olorun fi ife re han si oun ninu isoro ti o wa. O kunle si egbe ibusun re, o yonda aye re fun Jesu Kristi.

Bi iwo na ba dabi Bensini, ti o nla isoro koja, ti o ba le ba a debi ese Jesu lati gba adura yi. Mo fe lati gbadura fun o, ki nki o ku orire nitoripe o ti bo kuro ninu ajaga Esu, o si ti ni iye titun ninu Jesu Kristi.

Ti o ba fe iwe pelebe yii si jowo kan si
https://www.ehcnigeria.org/bible-courses/

**Every Home for Christ Nigeria**

7, Adekunle Akala St., Off Fatai Irawo St.,
Ajao Estate, By International Airport Road,
Lagos

+234 (1) 293 2331 | +234 (0) 815 5501 000
+234 - 815 550 2000

info@ehcnigeria.org | www.ehcnigeria.org